# Ìlò Àyídà Orin Onígbàgbọ́ (Kírísítẹ́ẹ̀nì) Gẹ́gẹ́ Bí Orin Ìfẹ̀hónúhàn Nínú Ètò Ìṣèlú Ilẹ̀ Nàìjíríà

**Dayọ̀ Àkànmú, *Ph.D.***
*Dayoakanmu2002@yahoo.com*
*and*
**Rifqat Sánní**
*Opesan03@yahoo.co.uk*
*Department of Yoruba*
*Adéníran Ògúnsànyà College of Education*
*Ìjàníkin, Lagos State, Nigeria*

## Àṣamọ̀

*Orin gẹ́gẹ́ bíi káríayé àti ọ̀kan pàtàkì lára ẹ̀yà ewì alohùn Yorùbá jẹ́ ọ̀kan lára ọ̀nà tí ọmọ ènìyàn ń gbà láti gbé èrò ọkàn wọn jáde. Ọpọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ ni ó ti wà láti ẹ̀yìn wá nípa orin ṣugbọ́n kò fi bẹ́ẹ̀ sí èyí tí ó túṣu dé ìsàlẹ̀ kòkò lórí àyídà orin àwọn kírísítẹ́ẹ̀nì nínú ètò Ìṣèlú ìjọba tiwa-n-tiwa lórílẹ̀ èdè yìí. Ìyànjú láti mọ̀ bí a ṣe ń ṣe àmúlò àti ìtúpalẹ̀ èdè inú àyídà orin àwọn kírísítẹ́ẹ̀nì tí ó wà fún ìfẹ̀hónúhàn gẹ́gẹ́ bí ìpèdè tí kò lè mú àlàáfíà bá ìlú ni ó ṣe okùnfà iṣẹ́ yìí. Bébà yìí ṣe àmúlò Tíọ́rì Karl Marx gẹ́gẹ́ bíi tíọ́rì tí ó lè ṣàlàyé kíkún nípa ohun tí ó máa ń ṣokùnfà làásìgbò ọ̀rọ̀ Ìṣèlú àti ìdí tí àwọn ará ìlú ṣe gbọ́dọ̀ lo orin ìfẹ̀hónúhàn fun ìjàgbara wọn. Àyídà orin kírísítẹ́ẹ̀nì tí ó ń fi ẹ̀hónú hàn márùn-ún ni a dìídì yàn láti ara ìṣẹ̀lẹ̀ òṣèlú àtẹ̀yìnwá fún ìtúpalẹ̀ nítorí pé wọn ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìlò èdè tí ó lè dènà àlàáfíà ìlú nínú. Ìlànà ìṣọwọ́lo èdè ni a lò fún ṣíṣe ìtúpalẹ̀ ìlò èdè nínú àwọn orin náà. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, a ríi pé ìlò èdè inú àwọn orin ìfẹ̀hónúhàn yìí jẹ́ èyí tí ó ń ṣe*

*'ìkìlọ̀', 'ìdánilẹ́kun', 'tàbùkù', 'ṣépè' tàbí 'gbèrò ibi sí àwọn aláṣẹ ìlú àti olóṣèlú' tí ìṣèjọba wọn ń ni ará ìlú lára. Àyídà orín àwọn kírísítẹ́ẹ̀nì yìí jẹ́ orin ìfẹ̀hónúhàn ti ìgbàlódé èyí tí àwọn ará ìlú fi ń gbé èrò ọkàn wọn jáde nígbàkúùgbà tí àwọn olóṣèlú tàbí aláṣẹ ìlú bá ń fi ìjọba wọn ni ará ìlú lára. Ṣùgbọ́n ó tún lè pa àlàáfíà ìlú lára nígbà tí irú orin bẹ́ẹ̀ bá bọ́ sí òdì lára àwọn aláṣẹ ìlú.*

**Kókó ọ̀rọ̀:** Àyídà orin, kírísítẹ́ẹ̀nì, ìfẹ̀hónúhàn, olóṣèlú, ìjàgbara, ìtúpalẹ̀.

## Ìfáárà

Òdú ni ọ̀rọ̀ orin jẹ gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára lítíréṣọ̀ Yorùbá àti nínú ètò ìgbésí ayé ọmọ ẹ̀dá, kìí ṣe àìmọ̀ fún olóko; ìdí nìyí tí orin fi jẹ́ kárí ayé àti pé kò sí ibi tí a kìí tí dáná alẹ́ ọbẹ̀ yóò kàn dùn ju ara wọn lọ ni. Kò sí ibi tí a kìí tí kọrin ní orílẹ̀ àgbáyé, orin kàn lè yàtọ̀ síra wọn ni, bóyá nípa àgbékalẹ̀ wọn àti èdè tí a ṣe àmúlò àti ìgbà tí a máa ń kọ wọ́n. Iṣẹ́ ti pọ̀ rẹpẹtẹ lórí orin kíkọ síwájú àkókò yìí láti ọ̀dọ̀ àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ káàkiri àgbáálá ayé nínú èyí tí Yorùbá kò gbẹ́yìn.

Lára àwọn onímọ̀ yìí ni a ti rí Ọlátúnjí (1984), Àlàbá (1992), Adégbìtẹ́ (1995), Agbájé (2013;1995), Kúkọ̀yí (1995), Adédèjì (2004), Dáramọ́lá (2008), Ajíbádé (2011), Ọmọ́jọlà (2017) àti Òjó et al (2018). Ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn onímọ̀ yìí ni wọ́n rí orin gẹ́gẹ́ bíi ẹ̀yà ewì alohùn nígbà tí àwọn mìíràn rí orin gẹ́gẹ́ bí ohun tí a fi ń ṣètò ìlú, ohun tí a fi ń tún ìwà ara ẹni ṣe àti ohun tí a fi ń gbé èrò ọkàn ẹni jáde. Kò sí atótónu tí àwọn onímọ̀ sọ nípa orin tí kò wúlò nínú iṣẹ́

yìí àti pé lára èròǹgbà iṣẹ́ yìí ni pé orin jẹ́ èròjà tí a fi ń gbé èrò ọkàn ẹni sí gbangba.

Oríṣìírisìí orin ni ó wà nílẹ̀ Yorùbá èyi tí àṣà àti ìṣe Yorùbá fi ààyè gbà. Lára àwọn orin náà ni orin ìrẹmọ, orin ìdárayá, orin ajẹmẹ́sìn àti orin ìfẹ̀hónúhàn tí iṣẹ́ yìí dá lé lórí. Ìyànjú láti ṣe àtúpalẹ̀ ìlò èdè inú orin àwọn kírísítẹ́ẹ̀nì tí a ṣe àyídà rẹ̀ sí orin ìfẹ̀hónúhàn ti ìgbàlódé, èyí tí ó lè dènà àlàáfíà orílẹ̀ èdè Nàìjíríà nínú ètò òṣèlú àti nírú àkókò yìí tí ìpèdè ìkóòríra ti fẹ́ẹ̀ da orílẹ̀ èdè yìí rú tán, ni ó ṣokùnfà iṣẹ́ yìí.

## Orin Ìfẹ̀hónúhàn

Ọkan lára ẹ̀yà orin tí ó wà ninú àṣà Yorùbá ni orin ìfẹ̀hónúhàn jẹ́ àti pé ṣàṣà ni àwùjọ tí kìí lo orin tàbí ọ̀rọ̀ sísọ fún ifẹ̀hónúhàn àyafi tí kò bá sí ètò ìṣejọba nínú àwùjọ bẹ́ẹ̀ ló kù. Orin ìfẹ̀hónúhàn jẹ́ irú orin kan tí àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn máa ń kọ nígbàkúùgbà tí àwọn alákòóso, aláṣẹ, olórí orílẹ̀ èdè tàbí olórí ilé iṣẹ́ kan bá ń fi ètò ìṣèjọba wọn ni àwọn òṣìṣẹ́ tàbí ará ìlú lára.

Fífi ara ni àwọn òṣìṣẹ́ tàbí ará ìlú lè jẹ́ nípa àìbìkítà ìjọba, aláṣẹ ilé iṣẹ́ àti àwọn olóṣèlú láti pèṣè ìgbé ayé tó rọrùn bíi ilé gbígbé, ètò ẹ̀kọ́, ààbò tó péye, ilé ìwòsàn tó dájú, ṣíṣe ọ̀nà tó já gaara, iná mọ̀nàmọ́ná, omi tó yè kooro, ètò ìmọ́tótó àti àwọn ohun a-máyé-dẹrùn mìíràn. Ó tún lè jẹ́ àìbìkítà láti pèṣè iṣé fún ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn ọ̀dọ́ tí kò níṣẹ́ lọ́wọ́ àti àṣà kíkó owó ìlú lọ sí òkè òkun fún ìgbádùn àwọn olóṣèlú nìkan.

Irú àwọn ohun tí a mẹ́nu bà yìí ni ó máa ń fa orin ìfẹ̀hónúhàn ní àwùjọ gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára àwọn ọ̀nà tí ará ìlú fi ń ja ìjàgbara fún ara wọn tàbí láti dẹ́kun àṣejù, àìbìkítà àti ìwà ìbàjẹ́ àwọn tí ó ń ṣàkóso ìlú. Ní kúkúrú, a lè sọ pé orin ìfẹ̀hónúhàn jẹ́ orin tí àwọn ará ìlú fi ń wa egbò dẹ́kun tàbí kìlọ̀ ìwà ìbàjẹ́ fún àwọn olóṣèlú àti àwọn aláṣẹ ìlú kan. Orin ìfẹ̀hónúhàn kò ṣàjèjì sí ilẹ̀ Yorùbá àti orílẹ̀ èdè Nàìjíría lápapọ̀. A ti gbọ́ nínú ìtàn rí, a sì ti gbọ́ nípa ìtándòwe tí ó sọ pé *ó kù dẹ̀dẹ̀ ká gbéwì dákẹ̀sán Aláàfin Jáyin tẹ́rí gbasọ (Adésànyà 2000:56)).* Iwì nínú ìsọ yìí dàbí orin ìfẹ̀hónúhàn ni àti pé kòbákùngbé ọ̀rọ̀ àti àṣírí tí ó wà nínú rẹ̀ ni Aláàfin náà kò fẹ́ gbọ́ títí tí ó fi ṣe ìṣe ọkùnrin.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé tíọ́rì Karl Marx tí a ṣe àmúlò rẹ̀ fi àlàkalẹ̀ àti àkóónú rẹ̀ ṣègbè lẹ́yìn ìfẹ̀hónúhàn lórí ọrọ̀ ìṣèlú àti ọ̀rọ̀ ajé, èròǹgbà iṣẹ́ yìí ni láti pàkíyèsí wa sí ìlò èdè inú orin ìfẹ̀hónúhàn pàápàá jùlọ àwọn tí ó lè ṣe àkóbá fún àlàáfíà orílẹ̀ èdè Nàìjíría nírú àkókò báyìí tó jẹ́ pé ọ̀rọ̀ tàbí ìpèdè ìkórìíra ti fẹ́ da orílẹ̀ èdè yìí rú.

## Tíọ́rì Karl Marx (Marxism Theory)

Tíọ́rì Karl Marx tí ó gbé kalẹ̀ láàrin ọdún (1818 - 1883) àti ẹnìkejì rẹ̀ Angela (1820-1895) ni a yàn láàyò fún iṣẹ́ yìí. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn àwòròṣàṣà onímọ̀ méjèèjì yìí kò fi tíọ́rì yìí wo tìfun-tẹ̀dọ̀ iṣẹ́-ọnà lítírésọ̀ kankan rí, àwọn ọmọlẹ́yìn wọn bíi Caudwell (1937) àti àwọn miiran ti lo 'Marxism' gẹ́gẹ́ bí òṣùnwọ̀n lámèyító fún yíyanjú orísìí iṣẹ́-ọnà lítírésọ̀.

Tíọ́rì yìí dá lórí ètò ọ̀rọ̀ ajé àti ìṣèlú gẹ́gẹ́ bí kókó pàtàkì tí ó so àwùjọ ró èyí tí ó máa ń fa ìjẹgàba àwọn aláṣẹ tàbí alákòóso ìlú tí kókó méjéèjì yìí wà ní ìkáwọ́ wọn lórí àwọn ará ìlú tí wọn ń darí. Tíọ́rì yìí ń ṣàlàyé ipa tí ọrọ̀ ajé àti ọ̀rọ̀ ìṣèlú ń kó ní àwùjọ àti lórí ìwà àti ìṣe àwọn ènìyàn àwùjọ kan. Òun náà ní ó ń sọ nípa irú ìdàgbàsókè tí ó dé bá àwùjọ àti ìdí tí àwùjọ kan fi yàtọ̀ sí àwùjọ mìíràn ní àkókò kan sí èkejì. Tíọ́rì yìí náà ni ó ṣe àpèjúwe irú àwọn ọ̀wọ́ tí ó wà ní àwùjọ gẹ́gẹ́ bí àwọn olówó/ọlọ́rọ̀ àti mẹ̀kúnnù. Ó jẹ́ kí á mọ̀ pé àwọn ọlọ́rọ̀ ni ó sábà máa ń di ètò ọrọ̀ ajé àti ìṣèlú mú àti pé àkùkọ gàgàrà tí kìí fẹ́ kí tabẹ́ rẹ̀ kọ ni àwọn ọlọ́rọ̀ yìí ni àwùjọ. Wọ́n fẹ́ kí àwọn máa wà lókè nígbà gbagbo, wọn kò fẹ́ jábọ́ rárá ṣùgbọ́n àwọn mẹ̀kúnnù náà kò fẹ́ wà ní ojú kan náà rárá, àwọn náà fẹ́ wà nípò ọlọ́lá.

Tíọrí yìí mẹ́nu ba ìjàdù ipò ní àwùjọ èyí tí ó máa ń dá yánpọn yánrin sílẹ̀ ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà. Tíọ́rì yìí ti mọ àrísá àti ìṣesí àwùjọ ni àlàkalẹ̀ rẹ̀ ṣe tẹpẹlẹ mọ́ ìjàgbara kúrò ní oko ẹrú tàbí lọ́wọ́ àwọn alágbára tó ń jẹ gàba lórí àwọn tí kò ní agbára. Lára àlàkalẹ̀ tíọ́rì yìí ni pe iṣẹ́ ọnà gbọ́dọ̀ máa ṣègbè lẹ́yìn àwùjọ tí àwọn arẹ́nijẹ ń jẹ gàba lé lórí (Adéyẹmí, 2006:39). Irú àlàkalẹ̀ báyìí gan an ni ó ṣokùnfà oríṣìí orin ìfẹ̀hónúhàn tí àwọn Ajìjàgbara, A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn, Ẹgbẹ́ Òṣìṣẹ́ àti Ẹgbẹ́ Akẹ́kọ̀ọ́ máa ń kọ nígbàkúùgbà tí wọ́n bá ṣàkíyèsí pé ìgbésẹ̀ tàbí ìṣèjọba àwọn aláṣẹ ilẹ̀ yìí ń fi ara ni àwọn ará ìlú nípa ọrọ̀ ajé àti ọ̀rọ̀ ìṣèlú gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹ jáde

nínú àyídà orin àwọn kírísítẹ́ẹ̀nì tó wá di orin ìfẹ̀hónúhàn èyí tí ó kún fún ìpèdè tí kò lè mú àlàáfíà bá ìlú.

## Ìtúpalẹ̀ Ìlò Èdè Inú Àyídà Orin Kírísítẹ́ẹ̀nì Gẹ́gẹ́ bí Orin Ìfẹ̀hónúhàn

Abala yìí ní a ti ṣe ìtúpalẹ̀ àyídà orin àwọn kírísítẹ́ẹ̀nì gẹ́gẹ́ bí orin ìfẹ̀hónúhàn ti òde òní. Orin A-jẹ-mọ́-ẹ̀sìn-kírísítẹ́ẹ̀nì jẹ́ orin tí àkóónú rẹ̀ ní ọ̀rọ̀ inú Bíbélì nínú tí ó sì kún fún àwọn ìsọ tí ó jẹ́ ti ẹ̀mí, àdúrà, ọpẹ́, ìyìn àti ìjọ́sìn fún àwọn kírísítẹ́ẹ̀nì nìkan (Adégbìtẹ́, 1994; Adédèjì, 2004 àti Dáramọ́lá 2008).

Àwọn àkóónú inú orin àwọn Kírísítẹ́ẹ̀nì tí a mẹ́nu bà yìí gan an ni àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn pa kádàrá wọn dà sí orin ìfẹ̀hónúhàn. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn orin tí a gbé yẹ̀wò lábẹ́ ìsọ̀rí yìí jẹ́ èyí tí a rí gbà sílẹ̀ nínú ìṣẹ̀lẹ̀ ètò ìṣèlú àti ọ̀rọ̀ ajé àtẹ̀yìnwá tí ó so mọ́ ìjọba àpapọ̀, ti ìpínlẹ̀ àti àwọn alákòóso ilé ẹ̀kọ́ gíga ti orílẹ̀ èdè yìí lọ́rùn, nígbà tí wọ́n bá gbé ìgbésẹ̀ tí ó ni ará ìlú lára. Lara awọn orin naa ni:

**(i)** ***Orin Ìfẹ̀hónúhàn A pe Ẹmí Ìjà Wọlé***

Èyí ni orin tí àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn máa ń lò láti fi ṣíde ìfẹ̀hónúhàn wọn, àti pé Ìlànà bí a ṣe ń kọrin ìjọ́sin nínú Ṣọ́ọ̀ṣì bi orin ìsàlẹ̀ yìí ní orin náà tẹ̀lé.

Wọ̀ ọ́ 'lé wá
Wọ̀ ọ́ 'lé wá o
Ẹ̀mí Àdúrà
Wọ ọ 'lé wá o.

Àwọn ọmọlẹ́yìn Kírísítì àti ìjọ Aládura ni wọn máa ń lò orin òkè yii láti fi pe ẹ̀mí tàbí agbára àdúrà wọlé nígbàkúùgbà tí wọ́n bá ń jọ́sìn tàbí ṣètò àdúrà pàtàkì nílé ìjọ́sìn. Ní kété tí wọ́n bá kọ orin yìí ni àwọn ènìyàn yóò ti mọ̀ pé ẹ̀mí àdúrà ti gbé wọn wọ̀ tí àdúrà gbígbóná yóò sì máa jáde lákọlákọ. Nínú Orin òkè yii, *Àdúrà* jẹ ọ̀rọ̀ tí àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn, Ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ àti ẹgbẹ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ṣe àyídà rẹ̀ sí *Àlútà* nínú orin ìfẹ̀hónúhàn tí wọ́n máa ń kọ nígbàkúùgbà tí ìjọba tàbí àwọn alákòóso ilé ẹ̀kó bá gbé ìgbésẹ̀ tí ó ni àwọn ará ìlú tàbí akẹ́kọ̀ọ́ lára:

Wọ̀ ọ́ 'lé wá
Wọ̀ ọ́ 'lé wá o
Ẹ̀mí *Àlútà*
Wọ ọ́ 'lé wá o

*Àlútà* jẹ́ àyídà *Àdúrà* tí í ṣe ọ̀rọ̀ inú Bíbélì èyí tí àwọn Kírísítẹ́ẹ̀nì ń lò fún ẹ̀bẹ̀ tàbí tọrọ nǹkan lọ́dọ̀ Ọlọ́run. Bí *Àdúà* ṣe jẹ́ ọ̀rọ̀ àyálò tí a yá wọnú èdè Yorùbá láti inú èdè Lárúbáwá náà ni *Àlútà* ṣe jẹ́ ọ̀rọ̀ àyálò tí ó wọnú èdè Yorùbá láti inú èdè Potogí àti Látìnnì. Nígbà tí *Àdúà* jẹ́ 'ìpèdè ìjọ́sìn àti ẹ̀bẹ̀' fún ohunkóhun láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run, *Àlútà* túmọ̀ sí 'ìjàgbara'/*'ìlàkàkà/ìjàngbọ̀n'(Wikipedia)*.

Nínú àpẹrẹ orin méjéèjì yìí, ó hàn dájú pé nígbà tí àwọn Kírísítẹ́ẹ̀nì ń pe ẹ̀mí 'ẹ̀bẹ̀' àti Ìjọsìn (àdúrà) láti gbé wọn wọ̀, àwọn a-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn, ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ àti àwọn ẹgbẹ́ akẹ́kọ̀ọ́ ń pe ẹ̀mí ìjàngbọ̀n/ìlàkàkà (*àlútà*) tí í ṣe wàhálà tàbí ìdàrúdàpọ̀ pé kí ó gbé àwọn wọ̀. Ní òtítọ́, wọ́n lè jà fún ẹ̀tọ́ lábẹ́ òfin ní ìbámu pẹ̀lú ọ̀kan lára àlàkalẹ̀ tíọ́rì Karl

Marx ti o fi ààyè gba kí àwọn ará ìlú gba ara wọn sílẹ̀ kúrò lọ́wọ́ ìjọba arẹ́nijẹ tàbí kí iṣẹ́ ọnà ṣe àtakò ètò ìmúnisìn láti ọ̀dọ̀ ìjọba, ṣùgbọ́n kò lè rọgbọ kí ohun méjì tí kò tọ̀nà di ohun tí ó tọ̀nà àti pé orí bíbẹ́ kọ́ ni òògùn orí fífọ́. Ìdí ni pé, nígbàkúùgbà tí ẹ̀mí ìjàngbọ̀n bá wọnú àwọn ènìyàn yìí, rògbòdiyan, ìdàrúdàpọ̀ àti yánpọnyánrin tí ó lè dí àlàáfíà ìlú lọ́wọ́ ni ó máa ń ṣẹlẹ̀.

***(ii) Orin Ìfẹ̀hónúhàn Ajẹmọ Ìbínú àti Èpè***

Èyí ni orin àwọn Kírísítẹ́ẹ̀ṇì tí àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn máa ń kọ́ nígbà tí inú bá bí wọn lórí ìwà ìrẹ́jẹ tàbí àìtọ́ tí àwọn olórí ìlú hù sí àwọn ará ìlú. Orin yìí wà lára orin tí àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn kọ ní ọdún 2012 láti fi ẹ̀hónú wọn hàn sí ìjọba Dókítà Goodluck Jonathan lórí ọ̀rọ̀ owó epo rọ̀bì tí a ó máa ṣàlàyé rẹ̀ níwájú. Orin naa máa ń ní èpè nínú nígbà mír̀an àti pé, àyídà orin Ṣọ́ọ̀ṣì`isàlẹ̀ yìí ni wọ́n sọ di ti ẹ̀hónú:

Áwá yóo mà yín Ọ
Áwá yóo má gbe Ọ ga
Íwọ ṣá ma ṣàtìlẹ́yìn wa
Áwá yóo má gbe Ọ ga

Orin ìyìn, ẹ̀bẹ̀ àti ìjọ́sìn sí Ọlọ́run ni orin àwọn kírísítẹ́ẹ̀nì yìí jẹ́ tí a bá wò ó ní àwòfín àti pé àwọn ìpèdè ìyìn, ẹ̀bẹ̀ àti ìjọ́sìn inú orin yìí ni àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn ṣe àtinúdá àti àyídà rẹ̀ nínú orin ìsàlẹ̀ yìí sí ìpèdè *èébú* àti *èpè* bíi *ṣẹ̀wá, fọ́wa jẹ, omi ló máa gbé ọ lọ,* àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ìṣewẹ́kú ohùn náà tún ran irú àyídà báyìí lọ́wọ́ nítorí pé ohùn tí àwọn kírísítẹ́ẹ̀nì fi gbé orin wọn kalẹ̀ kò yàtọ̀ sí

èyí tí àwọn a-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn fi ṣe àgbékalẹ̀ ti wọn náà lọ́nà tó jẹ́ pé bí ènìyàn kò bá tètè ṣe àkíyèsí àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ tí ó jẹ́ *èébú* àti *èpè*, ènìyàn yóò rò pé àwọn kírísítẹ́ẹ̀nì ni ó ń kọrin ni.

Jónáthán ti *ṣẹ̀wá*
Jónáthán ti fọ́wa jẹ
Gbógbó wá ti padà lẹ́yìn rẹ
Omi ló ma gbé ọ lọ

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ tẹ́lẹ, láti inú orin àwọn kírísitẹ́ẹ̀nì ni àyídà orin òkè yìí ti jáde àti pé àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn, Ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ àti Ẹgbẹ́ àwọn akékọ̀ọ́ pẹ̀lú àwọn ọmọ orílẹ̀ èdè yìí mìíràn ni ó ṣe àyídà orin náà ní ọdún 2012 ní ìlú Èkó nígbà tí wọn ń fi ẹ̀hónú wọn hàn lórí bí Ààrẹ orílẹ̀ èdè yìí nígbà kan rí ṣe yọ ọwọ́ kúrò nínú owó ìrànlọ́wọ́ tí ìjọba àpapọ̀ ń san lórí epo rọ̀bì kí ó lè rọ ará ìlú lọ́rùn gbẹ̀dẹ̀ ṣùgbọ́n tí ìgbésẹ̀ rẹ̀ yìí wá jẹ́ kí ara ni àwọn ọmọ orílẹ̀ èdè yìí nígbà náà.

Àwọn ọ̀rọ̀ bíi *ṣẹ̀ wá* àti *fọ́ wa jẹ* gan an ni ìpèdè tí ó ń ṣe àfihàn ẹ̀hónú tí àwọn ènìyàn ń fi hàn. *ṣẹ̀ wá* jẹ́ ìpèdè tàbí ìsọ ojoojúmọ́ nígbà tí *fọ́ wa jẹ* jẹ́ àkànlò èdè tuntun tí ó túmọ̀ sí *kí ènìyàn ṣẹ̀ ènìyàn, mú ènìyàn bínú, tàbí dalẹ̀.* Ìpèdè tí ó burú jù nínú àyídà orin náà ni *èpè*, *omi ló máa gbé ọ lọ* èyí tí ó lè gba òdì lára olórí orílẹ̀ èdè tí à ń ṣépè fún, tí ó sì tún lè ṣàkóbá fún àlàáfíà ìlú tí irú olórí bẹ́ẹ̀ bá jẹ́ alágídí ọkàn àti olórí kunkun tí ara rẹ̀ kọ ìwọ̀sí. Ó lè tipasẹ̀ èyí pàdí ọrẹ́ dà kí ó sì lo agbára rẹ̀ láti fìyà jẹ àwọn afẹ̀hónúhàn. Bí tíọ́rì ìṣàmúlò fún iṣẹ́ yìí tilẹ̀ faramọ́ ìfẹ̀hónúhàn, kò dájú pé ìpèdè

èpè tí ó lè dènà àlàáfíà ìlú ni ó ní kí wọ́n máa lò. Ní gbàgadè ìfẹ̀hónúhàn yìí kan náà ní wọ́n tún ti fi àyídà orin kírísítẹ́ẹ̀nì tí ó kàn yìí bú Ààrẹ tí à ń sọ nípa rẹ̀:

### (iii) *Orin Ìfẹ̀hónúhàn Ajẹmọ́ Èébú tààrà*

Èébú tààrà ni àkoónú inú orin yìí àti pé ìgbà tí àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn rí i pé ìjọba Goodluck Jonathan ń fi ara ni àwọn ará ìlú láìbìkítà lórí yíyọwọ́ owó ìrànwọ́ tí ìjọba ń fi kún owó epo rọ̀bì kúrò ní ọdún 2012 ni wọ́n ṣe àyídà orin Kírísítẹ́ẹ̀nì ìsàlẹ̀ yìí sí èyí tí ó jẹ́ kìkìdá èébú nínú ìfẹ̀hónúhàn wọn.

O ti mú wa gbàgbé o
Ìbànújẹ́ ìgbà kan
O ti mú wa gbàgbé o
Ìbànújẹ igba kan
À ṣé wẹ́rẹ́ niṣe Olúwa
Ọba tí a pè tó ń jẹ́
À ṣé wẹ́rẹ́ niṣẹ́ Olúwa
Ọ̀ba tí a pè tó ń jẹ́.

Orin ìyìn àti ọpẹ́ sí Ọlọ́run fún ohun ribiribi tí Ó ṣe fún àwọn kírísítẹ́ẹ̀nì ni orin yii jẹ́ ṣugbọ́n àwọn Ẹgbẹ́ àwọn òṣìṣẹ́ àti àwọn Ẹgbẹ́ A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn pẹ̀lú ẹgbẹ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ṣe àyídà orin yìí sí ti ìfẹ̀hónúhàn nígbà làásìgbò ọ̀rọ̀ yíyọ owó ìrànwọ́ tí ìjọba ń san lórí epo rọ̀bì fún àwọn ará ìlú kúrò ní ọdún 2012 báyìí pé:

O ti yára gbàgbé o
Ìlérí rẹ igbà kan,
O ti yára gbàgbé o

Ìlerí rẹ igbà kan
Jónáthàn!
À ṣé bíńtín lọgbọ́n orí rẹ
Ìwọ tí a rò pó gbọ́n ọn
À ṣé bíńtín lọgbọ́n orí rẹ
Ìwọ tí a rò pó gbọn.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ilé-iṣẹ́ amóhùnmáwòrán ní ó ṣe àfihàn ìfẹ̀hónúhàn náà bí ó ṣe ń lọ lọ́wọ́. Lára àwọn ilé-iṣẹ́ amóhùnmáwòrán náà ni AIT (African Independent Television) àti TVC (Television Continental) tí ó wà ní ìpínlẹ̀ Èkó. Àwọn ọ̀rọ̀ ọpẹ́ àti ìyìn tí ó wà nínú orin kírísítẹ̀ẹ̀nì náà ni a ṣe àyídà rẹ̀ sí ìpèdè èébú. Nígbà tí àwọn kírísítẹ̀ẹ̀nì ń fi orin tiwọn dúpẹ́ pé *Ọlọ́run ti mú wọn gbàgbé Ìbànújẹ́ ìgbà àtijọ́,* àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn ń fi tiwọn bú èébú pé *Ààrẹ Jónáthàn ti yára gbàgbé Ìlérí rẹ ìgbà kan.* Bákan náà, nígbà tí àwọn kírísítẹ̀ẹ̀nì ń fi orin wọn yin Ọlọ́run láti mọ rírì Rẹ̀ pé *à ṣé wẹ́rẹ́ nìṣẹ́ Olúwa, Ọba tí a pè tó ń jẹ́,* àwọn a-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ ènìyàn ṣe àyídà rẹ̀ sí ìpèdè èébú wí pé *à ṣé bíńtín lọgbọ́n orí rẹ ìwọ tí a rò pó gbọ́n.*

Èébú ńlá gbáà tí ó lè mú kí ẹni tí a fi orin bú gbaná jẹ ni kí a sọ pé *bíńtín lọ́gbọ́n orí èèyàn tàbí ìwọ tí a rò pé o gbọ́n,* ó sì tàbùkù Ààrẹ Jonathan gẹ́gẹ́ bí Ààrẹ orílẹ̀ èdè àkọ́kọ́ tí ó kẹ́kọ̀ọ́ gboyè ọ̀mọ̀wé tí ó sì kàwé ju gbogbo Ààrẹ tí a ti ní sẹ́yìn lọ. Nínú orin ìfẹ̀hònúhán yii, *o ti yára gbàgbé ìlérí rẹ ìgbà kan* jẹ́ ìpèdè èébú èyí tí ó sọ Ààrẹ Jonathan di òpùrọ àti ẹni yẹpẹrẹ nítorí ìlérí tí ó ṣe fún àwọn ọmọ orílẹ̀ èdè yìí gẹ́gẹ́ bi ẹni tí ó ti wà ní ipò tálákà rí, tí àwọn òbí rẹ̀ kò

sì rówó ra bàtà ilé ìwé fún un nígbà tó wà ní kékeré wí pé òun kò ní fi ara ní wọ́n.

Lóòótọ́ ni pé tíọ́rì Karl Marx fi àyè gba ìjàgbara nínú èyí tí a ti lè rí orin ìfẹ̀hónúhàn ṣugbọ́n irú orin báyìí kò tàbùkù Olórí orílẹ̀ èdè wa nìkan, ó tún tàbùkù orílẹ̀ èdè yìí àti àwọn ọmọ orílẹ̀ èdè yìí gan an. Bí ìgbà tí ènìyàn bá ń wọ́ ara rẹ̀ nílẹ̀ ni àti pé tí Ààrẹ Jonathan bá jẹ́ Ààrẹ tí ó ya ìkà, ọ̀dájú àti olóríkunkun gẹ́gẹ́ bí àwọn Ààrẹ kan tí a mọ̀ nínú ìtàn, ó lè lo agbára rẹ̀ lórí àwọn afẹ̀hónúhàn ní ọ̀nà òdì èyí sì lè dènà àlàáfíà ìlu.

***(iv) Orin Ìfẹ̀hónúhàn tó fi Ọlọ́run hàn bí Aṣègbè-mẹ̀kúnnù***

Èyí ni orin ìfẹ̀hónúhàn tí ó fi ìgbàgbọ́ àwọn Ajàfẹ́tọ̀ọ́ ọmọ ènìyàn hàn nínú Ọlọ́run gẹ́gẹ́ bí Ọba Olùgbèjà tí ó lè gba ènìyàn sílẹ̀ lọ́wọ́ ẹni tí apá rẹ̀ kò ká. Orin Kírísítẹ́ẹ̀nì ìsàlẹ̀ yìí tí òun náà fi agbára Ọlọ́run hàn gẹ́gẹ́ bí ọba tí ó lè ṣe ohun gbogbo ni àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ ènìyàn ṣe àyídà rẹ̀ nínú ìfẹ̀hónú hàn tí a ó ṣe àlàyé ohun tó fa sábàbí rẹ̀ nísàlẹ̀ yìí.

Alágbárá lọlọ́run wà
Àlàgbàrà ní Jesù wa
Ọba tó layé àt'ẹ̀kún rẹ ní ìkawọ́
Kó ma s'ohun tí kò le ṣé

Orin àwọn Kírísítẹ́ẹ̀nì tí ó wà fún yíyin Ọlọ́run àti mímọ rírì agbára Ọlọ́run ni orin òkè yii ṣùgbọ́n àwọn Afẹ̀hónúhàn lo ọgbọ́n àtinúdá tiwọn láti ṣe àyídà orin náà báyìí:

Alágbárá lọlọ́run wà

Àlàgbàrà ní Jesù wa
Ọba tó pa Sánní Abacha
Láì lo kóńdó
Kò mà sẹ́ni tí kò le pá.

Tí a bá ṣe àkíyèsí orin ìfẹ̀hónúhàn yìí dáadáa, a ó ri pé bí àwọn Kírísítẹ́ẹ̀nì ṣe kọ tiwọn ní ìlà àkọ́kọ́ àti ìlà kejì ni àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ ènìyàn tàbí àwọn Ajìjàgbara náà ṣe kọ tiwọn:

Álágbárá lọlọ́run wà
Àlàgbàrà ní Jesù wa

Kò sí ìyàtọ rárá nínú ìlà méjéèjì òkè yìí ṣùgbọ́n àwọn tó sọ orin náà di orin ìfẹ̀hónú hàn ṣe àyídà àwọn ìlà tí ó kù gẹ́gẹ́ bí ìpèdè *ìyìn* tí o tún ń tọ́ka sí mímọ rírì agbára Ọlọ́run sí ìpèdè *láabi* lọ́nà tí òun náa fi ṣe àfihàn agbára Ọlọ́run nítorí pé kò sí ẹni tí ó rò pé Abacha lè kú ní àkókò náà bí ohun gbogbo ṣe kan bóbó tó lórílẹ̀ èdè Nàìjíríà:

Ọba tó layé àti ẹ̀kún un rẹ̀ ní ìkáwọ́
Kò mà s'óhun tí kò lè ṣe

Àwọn ìlà tí ó parí orin kírísítẹ́ẹ̀nì òkè yìí ni àwọn Ajìjàgbara àti àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ ènìyàn yípadà sí:

Ọba tó pa Sanni Abacha
Láì lo kóńdó
Kò mà sẹ́ni tí kò lè pa

Ohùn tí a fi gbé orin méjéèjì yìí kalẹ̀ kò yàtọ̀ rára àyàfi ìpèdè *ikú* nínú ọba *tó pa Sánní Abacha láì lo kóńdó* àti *kò mà sẹ́ni tí kò lè pa*, tí ó jẹ́ ìpèdè láabi. Ìpèdè yìí jẹ ọ̀rọ̀ láabi nítorí pé àṣà Yorùbá kò fi ààyè gba ríro ikú ro ènìyàn tàbí ká fi ikú yọ

ènìyàn bí ó ti wù kí ẹni náà burú tó. Sánni Abacha tí a lo orúkọ rẹ̀ nínú orin ìfẹ̀hónúhàn yìí jẹ́ olórí orílẹ̀ èdè yìí tó kú sórí oyè ní ọjọ́ kẹ̀jọ, oṣù kẹfà ọdún 1998 nígbà tí ẹnikankan kò lérò. Ìdí ni pé, lẹ́yìn tí olóògbé M.K.O. Abíọ́lá díje du ipò olórí orílẹ̀ èdè yìí ní ọdún 1993 tí ẹ̀rí sì fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ó jáwé olúborí kí wọn tó fagi lé ìbò náà di ẹni tí a gbé jù sí àtìmọ́lé nígbà tí ó jà fún ẹ̀tọ́ rẹ̀ lábẹ́ ìjọba Abacha. Ìrètí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ orílẹ̀ èdè yìí ni pé Sánní Abacha yóò gbé ìjọba sílẹ̀ fún olóyè Abíọ́lá ṣùgbọ́n dípò kí ó ṣe èyí, ó bẹ̀rẹ̀ sí ní fi ìjọba rẹ̀ ni ara ilu lára, ó sì tún fẹ́ sọ ara rẹ̀ di Ààrẹ olóṣèlú. Nínú èyí ní ìlú wà tí Sání Abacha fi kú láìrò tẹ́lẹ̀.

Orin ìfẹ̀hónúhàn yìí ni àwọn afẹ̀hónúhàn lò láti fi pẹ̀gàn Abacha kí ó tó di pé Abíọ́lá fúnra rẹ̀ náà jẹ́ Ọlórun nípè lẹ́yìn ọjọ́ díẹ̀ tí Abacha kú. Láti ìgbà náà ni àwọn afẹ̀hónúhàn, ti sọ orin yìí di orin ìfẹ̀hónúhàn tí wọ́n máa ń kọ fún àwọn olórí, aláṣẹ tàbí alákoso tí wọ́n nígbàgbọ́ pé ó burú tabi tí ó níkà nínú tí ètò ìṣèjọba rẹ̀ tún ni ará ìlú lára.

### *(v) Orin Ìfẹ̀hónúhàn sí Ìjọba lórí Ọ̀wọ́ngógó Ọjà*

Èyí ni orin ìfẹ̀hónúhàn tí àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn máa ń kọ láti fi ẹ̀hónú wọn hàn sí ìjọba nígbàkúùgbà tí ọjà bá gbówó lórí tí ìjọba kò sì gbìyànjú láti ṣe àtúnṣe. Orin yìí kìí ní èpè tàbí èébú nínú bẹ́ẹ̀ sì ni kìí ní ọ̀rọ̀ àfojúdi nínú rárá àti pé, àyídà orin àwọn Kírísítẹ́ẹ̀nì ìsàlẹ̀ yìí ni:

Ò yẹ ká dúpẹ́
Ó yẹ ká dúpẹ́
Àrá n sán
Atẹ́gùn ń fẹ́

Ijí jà kò gbé wa lọ
Ó yẹ ká'dúpẹ́

Orin òkè yìí jẹ́ ọ̀kan lára orin àwọn kírísítẹ́ẹ̀nì tí ó kún fún kìkìdá *ìyìn* àti *ọpẹ́* sí Ọlọ́run fún ìpamọ́ àti ààbò Rẹ̀ lórí wọn èyí tí àwọn Afẹ̀hónúhàn ṣe àyídà rẹ̀ báyìí:

Ò yẹ ká bínú
Ó yẹ ká bínú
Gàrí wọ́n
Irésì wọ́n
Ebi ń pará ìlú
Ó yẹ ká dúpẹ́

Ní àkọ́kọ́, ìṣewẹ́kú ohùn wà nínú àgbékalẹ̀ orin méjéèjì eyi tí ó mú kí àyídà orin Kírísítẹ́ẹ̀nì náà rọ́rùn púpọ̀ sí ti ìfẹ̀hónúhàn. Ìṣewẹ́kú àmìn ohùn tí ó wà lórí àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ orúkọ bíi *àrá, atẹ́gùn* àti *ìjì* tí a ṣe àyídà wọn pẹ̀lú ẹyọ ọ̀rọ̀ orúkọ mìíràn bíi *gàrí, Ìrẹsì*, *ebi* àti ọ̀rọ̀ ìṣe *sán, fẹ́* àti *jà* tí àyídà wọn jẹ́ *wọ́n* àti *pa.* Yàtọ̀ sí ìṣewẹ́kú ohùn, ìṣewẹ́kú tún wà nínú ìdí tí àwọn ọ̀kọrin méjéèjì ṣe kọ orin wọn. Àwọn kírísítẹ́ẹ̀nì kọ orin tiwọn láti dúpẹ́ àti láti fi ẹ̀mí ìmoore wọn hàn sí Ọlọ́run fún ààbò Rẹ̀ lórí wọn (*àrá sán, atẹ́gùn fẹ́, ìjì jà*, tí ó jẹ́ mẹ́táfọ̀ fún *àjálù ńlá* tàbí *ohun burúkú*), nígbà tí àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn náà kọ ti wọn láti fi ẹ̀hónú àti ìbínú wọn hàn sí ìjọba lórí ọ̀wọ́ngógó oúnjẹ (*gàrí wọn, ìrẹsì wọn* àti *ebi ń pará ìlú* tí í ṣe mẹ́táfọ̀ fún *ìyàn*) nílùú. *Ó yẹ ká dúpẹ́* ni ìpèdè tí ó fi ẹ̀mí ìmòore àwọn kírísítẹ́ẹ̀nì hàn sí Ọlọ́run nígbà tí *ó yẹ ká bínú* jẹ́ ìpèdè tí ó fi ẹ̀hónú àti ìbínú àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn hàn sí ìjọba.

Orin òkè yìí jẹ́ àpẹ̀ẹrẹ orin ìfẹ̀hónúhàn tí kò tí ì burú jù láti fi ẹ̀hónú hàn lórí ìgbésẹ̀ Ìjọba tó bá mú ìnira lọ́wọ́ nítorí pé kò sí ọ̀rọ̀ èébú àti èpè nínú rẹ̀ èyí tí ó lè ṣe àkóbá fún àlàáfíà ìlú bíi ti àwọn tí ó kù.

Ìjọba tó bá mọ ohun tí ó ń ṣe kò yẹ kí ó bínú sí irú ìpèdè báyìí nítorí pé ẹ̀hónú gan an ni orin náà ń ṣe àfihàn an rẹ̀, ó yẹ kí ó gbé ìgbésẹ̀ láti ṣe àtúnṣe ni.

## Àbájáde Ìtúpalẹ̀

Lẹ́yìn gbogbo atótónu lóri àyídà orin àwọn Kírísítẹ́ẹ̀nì gẹ́gẹ́ bí orin ìfẹ̀hónúhàn nínú ètò ìṣèlú orílẹ̀ èdè yìí, a rí àyídà orin Kírísítẹ́ẹ̀nì tí a lò nínú iṣẹ́ yìí gẹ́gẹ́ bí orin ìfẹ̀hónúhàn tí àwọn tó ń jà fún ará ìlú fi ń gbé èrò ọkàn wọn jáde nígbàkúùgbà tí ètò tàbí ìgbésẹ̀ Ìjọba kan bá ń ni ará ìlú lára.

Nínú ìtúpalẹ̀ yìí náà ni ó ti hàn gbangba pé ìlò orin ìfẹ̀hónúhan kìí ṣe ohun tí kò tọ̀nà tí kò bá ní ìpèdè ìkóríra, èébú àti èpè tí ó lè dénà àlàáfíà ìlú nínú gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i nínú tíọ́rì Karl Marx tí ó tẹpẹlẹ mọ́ jíjà fún ẹ̀tọ́ ọmọ ènìyàn nígbàkúùgbà tí àwọn alágbára ayé bá fẹ́ fi ọwọ́ ọlá gbáni lójú. Ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí náà ló jẹ́ kí á rí ìṣewẹ́kú àlàkalẹ̀ tàbí kókó tí Karl Marx ń tẹpẹlẹ mọ́ nínú tíọ́rì rẹ̀ pé ó ń ṣokùnfà ìfẹ̀hónúhàn àti àwọn orin ìfẹ̀hónúhàn tí a lò nínú iṣẹ́ yìí.

Àrídájú tún wà nínú ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí pé àwọn ọ̀rọ̀ ẹ̀bẹ̀, ìjọ́sìn, ọpẹ́, ìyìn àti ọ̀rọ̀ inú Bíbélì mìíràn tí ó jẹyọ nínú orin àwọn Kírísítẹ́ẹ̀nì ni a ṣe àyídà wọn sí ìpèdè ìkóríra, èébú, èpè, ọ̀rọ̀ àbùkù àti ọ̀rọ̀ ìgànnìyàn nínú orin ìfẹ̀hónúhàn.

Ní àkótán, ó hàn gbangba pé ìpèdè tí ó ní èpè, èébú àti ọ̀rọ̀ àbùkù nínú jẹ́ ìpèdè ìkórìíra irú èyí tí ó ń lọ lọ́wọ ní orílẹ̀ èdè yìí lórí ẹ̀rọ ayélujára níbi tí àwọn ẹ̀yà kan ti ń sọ̀rọ̀ òdì, èébú, èpè àti ọ̀rọ̀ ìkórìíra sí Ààrẹ orílẹ̀ èdè yìí àti sí àwọn ẹ̀yà mìíràn lórí kókó ọ̀rọ̀ tí wọn kò lè fi àrídájú rẹ̀ múlẹ̀. Ó kù díẹ̀ kí irú ọ̀rọ̀ ìkóòríra báyìí da orílẹ̀ èdè yìí rú tán àti pé kò yẹ kí irú ìpèdè yìí máa wà nínú ìfẹ̀hónúhàn wa. Dípò irú orin bẹ́ẹ̀, àpẹẹrẹ orin tí a tú palẹ̀ gbẹ̀yìn dára díẹ̀ fún títa ìjọba lólobó lórí ìgbésẹ̀ Ìjọba tí ó lè fa ìnira fún ará ìlú kí àwọn Ìjọba náà sì ṣe àtúnṣe.

## Agbálọgbábọ̀

A ti ná ìgbárá a sì ti ná ìgboro lóri àyídà orin àwọn Kírísítẹ́ẹ̀nì gẹ́gẹ́ bí orin ìfẹ̀hónúhàn tí àwọn Ẹgbẹ òṣìṣẹ́, A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-enìyàn àti Ẹgbẹ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ máa ń kọ nígbàkúùgbà tí wọ́n bá wòye pé ìgbésẹ̀ Ìjọba ń ni ará ìlú lára.

Nínú iṣẹ́ yìí náà ni a ti mọ̀ pé ẹ̀tọ́ ọmọ ènìyàn ni láti fi ẹ̀hónú rẹ̀ hàn sí ìgbésẹ̀ Ìjọba tí ó bá ń ni ará ìlú lára gẹ́gẹ́ bí tíọ́rì Karl Marx tí a lò ṣe sọ ṣùgbọ́n pẹ̀lẹ́ ní akọ ó sì ní abo. Kò yẹ kí ọ̀rọ̀ ìkórìíra ,èpè, èébú, ìtàbùkù àti ìgànnìyàn máa wà nínú orin ìfẹ̀hónúhàn nítorí pé ó lè dí àlàáfíà ìlú lọ́wọ́ tàbí kí ó dá rúgúdù sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àwọn ọ̀rọ̀ ìkórìíra tí ó fẹ́ da orílẹ̀ èdè yìí rú nírú àkókò tí a wà yìí.

Ó yẹ kí orin ìfẹ̀hónúhàn jẹ́ orin ìpàrọwà, ìkìlọ̀ àti èyí tí ó ń pàkíyèsí ìjọba sí ìgbésẹ̀ tí ó lè ni ará ìlú lára kí ìjọba sì gbé ìgbésẹ̀ láti ṣe àtúnṣe. Kò yẹ kó jẹ́ orin èpè àti ìkórira tí ó

tún lè mú kí àwọn olórí tàbí aláṣẹ ìlú ṣi ìwà hù tàbí yíjú padà sí àwọn ará ìlú èyí tí ó lè tún fa ìdàrúdàpọ̀ kí ó sì dí àlàáfíà ìlú lọ́wọ́. Omi tútù ni ó ń tẹnu ẹja bọ́, ọ̀rọ̀ tútù ló yẹ kí ó máa ti ẹnu àwọn A-jà-fẹ́tọ̀ọ́-ọmọ-ènìyàn jáde nígbàkúùgbà tí ìdí bá wà fún kí wọ́n fi ẹ̀hónú hàn tàbí kí wọ́n jà fún ẹ̀tọ́ ará ìlú nítorí pé pẹ̀lẹ́ ni a fi máa ń pàmúkùrù pẹ̀lẹ́.

## Ìwé Ìtọ́kasí

Adédèjì, S.O (2004). *"Nigerian Gospel Music: A Study of Its Style".* Unpublished Ph.D. Thesis. Institute of African Studies, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Adégbìtẹ́, A. (1994). "The Influence of Islam on Yorùbá Music". *Oríta Ìbàdàn Journal of Religious Studies,*Vol. 1, No.2.

Adésànyà, A. O. (2000). ''Ìṣèlú Àbáláyé àti Ìṣèlú Òyìnbó: Èwo Ló ṣe Àkóbá fún Orílẹ̀ Èdè Nàìjíríà'' *Ọpáḿbàtà*. Vol. 2.1.

Adéyẹmí, L. (2006) *Tíọ́rì Lítíréṣọ̀ ní Èdè Yorùbá*, Ìjẹ̀bú-Òde: Ṣebíotimọ Publications.

Agbájé, B. (2013). ''A Literary Study of Songs in Selected Drama of Akínwùmí Ìṣọ̀lá''. *Emerging perspectives on Akínwùmí Ìṣọ̀lá*, Tóyìn Fálọlá & Túndé Akínyẹmí (Eds). Eriticea, World Industries & Press.

Agbájé, J.B (1995). *"A Literary Study of the Folksongs of the Èkìtì People of Nigeria''*. Unpublished Ph.D. Thesis, University of Ìlọrin, Ìlọrin.

Ajibádé, A.O. (2011). "New wine in old cups: post colonial Performance of Christian Music in Yorùbá Land''. *Studies in Word Christianity. Vol.13.*

Àlàbá, O. (1992). 'Ọgbọ́n Ìtọpinpin Ewì Yorùbá'. *Yorùbá Gbòde,* Vol. 1(8).

Caudwell, C. (1977). *Illusion and Reality*. London, Lawrence and Wishart.

Dáramọ́lá, A.M. (2008). "*The Musical concept of the Aláṣàlátù in Yorùbá Islamic Music".* Unpublished Ph.D. Thesis, Department of Music, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-ifẹ̀.

Eagleton, T.S. (1965). *Marxism and Literary Criticism*. Berkly and Los Angeles: University of California Press.

Kúkọ̀yí, E. (1995). "Gospel Music". *Praise the Lord News*. 2 (8), 6.

Òjó, I.F. et al (2018). ''Ìlò Orin àti Ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ gẹ́gẹ́ bí Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ fún Àmúdúró Àyípadà Rere Nínú Ètò Ìṣèjọba Tiwa-n-tiwa Lórílẹ̀ Èdè Nàìjíríà''. nínú Rájí, S.M.; Fájẹ́nyọ̀, R.; Adéríbigbé, M.M.; Adéṣuyan, R.A. àti Òjó, I.F. (Àwọn Olóòtú) *Èdè, Àṣà àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá: Ìtàn-ò-ní-gbàgbé yín*. Ìbàdàn: Masterprint Publishers.

Ọlátúnjí, O. (1984). *Features of Yorùbá Oral Poetry.* Ìbàdàn: University Press Limited.

Ọmọ́jọlà, B. (2017). ''Music and Dance'' *Culture and Performance* In Tóyìn Fálọlá and Akíntúndé Akínyẹmí (eds.). Austin, Pan-African University Press.

Wikipedia (https./en.m.wikipedia.org.